”Eyi ti o lẹtọọ julọ ninu awọn majẹmu lati mu ṣẹ ni nnkan ti ẹ fi sọ awọn abẹ di ẹtọ”

Lati ọdọ ‘Uqbah ọmọ ‘Aamir- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: ”Eyi ti o lẹtọọ julọ ninu awọn majẹmu lati mu ṣẹ ni nnkan ti ẹ fi sọ awọn abẹ di ẹtọ”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe dajudaju eyi ti o lẹtọọ julọ ninu awọn majẹmu lati mú ṣẹ ni nnkan ti o jẹ okunfa nibi sisọ igbadun pẹlu obinrin di ẹtọ, awọn ni awọn majẹmu ti o lẹtọọ ti iyawo maa n beere fun wọn nibi siso yigi.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/6021